2/7/77
IBADAN

11 JUL 1977

WEEKS 49&50
Kongi WK 49
8 19 28
Wk 50
27 34 48
Asiko BK W K 49
15 19 25 39
Wk 50
6 49 52 58
Ross Wk 49
3 & 42
WK 50
7&37

# Imole Owuro

ESIN ORO WA: IMOLẸ DE OKUNKUN PARADA!

SAMCO OF NIGERIA
WK 49
NAP 13 14 44
Perm 13 14 19 29 44
My Address ?
Not nessesary.
Always meet me in Imole Owuro Every Saturday

**2 6 16**

Independent Paper Vol. XV NO 803, SATURDAY JULY 2 — FRIDAY JULY 8 1977 10K. (KOBO MEWA)

# ỌMỌ TITUN DA WAHALA BỌ ỌLỌPA LỌRUN

WAHALA aṣeferẹku ni awọn Ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹ ilu Ogbomọṣọ bẹrẹ si i ṣe bayi l'ori ọrọ ọmọ titun kan ni ilu na.

Ohun ti o ko wahala ba awọn Ọlọpa l'ori ọrọ na ni pe, iya ọmọ na, Awaawu Ayọka ni o ke gbajare tọ wọn lọ pe, oju oun ri irikuri, ki nwọn gba oun.

Gẹgẹ bi mo ti gbọ, ọmọ ọjọ mẹrinlelogun kan ti awọn obi rẹ fẹ

LATI OWỌ
JOHN BAMIDELE,
OGBOMỌṢỌ

nawo ikojade rẹ ni ọla ọjọ kẹta oṣu keje ọdun yi, ni iya rẹ sọ pe oun tẹsilẹ l'ori bẹẹdi oun ti oun si lọ wẹ ni ile-iwẹ. O ni nigba ti oun pada wọle ni oun wa ọmọ na ti, ni oun ba fi igbe bọnu.

Gẹgẹ bi iya ọmọ na ti sọ fun mi, o ni lehin ti oun ati awọn alajọgbele oun wa ọmọ na ti awọn ko ri i ni ẹnikan la oun lọyẹ pe, ki oun lọ wo inu amu omi oun wo. O ni nigbati oun yio bojuwu bojuri, oku ọmọ na ni oun ba ninu amu na.

Iya ọmọ titun na sọ pe mehaaya ni onn jẹ ninu ile ti oun ngbe na ati pe enia meji miran ni awọn dijọ ngbe ile na ni adugbo Aiyegun nilu Ogbomọṣọ. Ni ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu kẹfa ọdun yi ni iṣẹlẹ na si ṣẹlẹ.

(Woju Ewe Kẹrin)

## 'Aboyun pa alabagbele re'

NWỌN ti mu obinrin aboyun kan, I y a b ọ Albert, ẹni ogun ọdun wa sile ẹjọ Grade II Magistrate Court nilu Kaduna lati koju ẹsun ipania.

Awọn afẹsunkanni fi ẹsun kan pe, obinrin aboyun na ti o ngbe ni B. B. Ibahim Taiwo Road, Tundu Wada Kaduna, mọ i mọ tu epo Karosinni inu stoofu idana ti o njo le Omidan Temilọla Akọmọlafẹ ti oun na jẹ ẹni ogun ọdun lori. Alajọgbele kanna ni awọn mejeeji iṣe.

Awọn afẹsunkanni sọ pe ni ọjọ kẹtala oṣu kẹfa ọdun yi ni iṣẹlẹ na ṣẹlẹ.

Ripẹtọ Ọlọpa kan ti o nka ẹsun si ọdaran na l'ọrun, Ọgbẹni Wycliff Damisa, sọ fun ile ẹjọ na pe, Obinrin aboyun na daran yi ni akoko ti oun ati oloogbe na nja

Gẹgẹ bi afẹsunkanni ti wi, lẹsẹkẹsẹ ti ọrọ na ṣẹlẹ ni nwọn sare gbe onitọhun lọ sile iwosan Ijọba n'ilu Kaduna nibi ti o ti jalaisi lẹhinorẹhin.

## Akiyesi Pataki

EYI ni lati tọrọ aforijin lowo ẹnyin onkawe wa pe, ile iṣẹ NEPA ni o pa ina ti a ko fi le gbe oju ewe mẹjo jade ninu osẹ yi.

Iṣoro yi ni a ti dojuko lati akoko diẹ sẹhin nitori titi nla ti nwon ngbekoja lo ni adugbo Yemẹtu ti a wa.

A lero pe a o bo kuro ninu wahala na laipẹ, a si ni ireti pe, ẹ o ba wa fi ifẹ gba a.

— OLOOTU

ALHAJI
DAUDA EPO-AKARA
TUN GBEDE O!

GBAJUMỌ ati olokiki, Ọba ninu Are Awurebe ni Naijiria, Alhaji Dauda Epo Akara ati ẹgbẹ alare Awurebe rẹ ti tun gbe pabambari are atata miran de ninu awo rẹkọọdu rẹ titun ti o ṣẹṣẹ ṣe, eyi ti nwọn ti bẹrẹ si i ta lati ọjọ Alamisi, ti iṣe ọgbọnjọ (30/6/77) oṣu kẹfa ọdun yi.

Gbogbo aiye ni o ti mọ pe, ọga ni Alhaji Epo Akara jẹ ninu are faaji asiko. Awo rẹ titun yi galọla, Koṣeemani ni fun gbogbo enia. Lara akọle rẹ ni:-

OJU KINNI
Mecca Special

OJU KEJI
Ọba Adebimpe Olubadan
Ẹgbẹ Owoniyi
Lasisi, Ọmọ Abẹrẹ
Mustafa Alasco, Kaduna
Itan ọrẹ meji.


ALHAJI EPO AKARA

Bakanna ni Awo ti gbajumọ Ọdọmọde Alapala nni, Rimmi Atọlagbe (Rolling System 1) ati ẹgbẹ Alapala rẹ na ti wa fun tita bayi. Awo Atolagbe yi na koyoyo, o le gongo.

Ẹ le ri awon awo rẹkoodu l'adugbo na ra ni gbogbo ile itaja nyin tabi taara l'odo:

ADETUNJI OMO AJE SOUND STUDIO

ADETUNJI STORES
2, Ibomo Street,
Agarawu, Lagos.

*Sw3/51 Adetunji House, Popoyemoja, Ibadan
*Sw6/431 Old Armels Rd. Ogunpa, Ibadan.

# ÌSỌ̀RỌ̀-N'ÍGBÈSÌ...

## IPADE (62)

Adeyẹmọ Ọjẹrinde
AGO onile l'oni o, Alayinde mi,
Ejiwande ara Ilagbẹdẹ,
Ọmọ Aworintunrinro,
Iremogun ọmọ Ayoyọ n'ile Ejigbọjọ.
Iyawo rẹ nkọ,
Ṣe nbẹ l'alaafia ara ?
Okele ko nii ha ọ l'ọrun
Ata ko ni i pa ọ l'ori.
Ṣe, o ko gbagbe ibi a bọrọ de ?
Ọmọ Ejigbọjọ, ṣoo gbagbe ọrọ wa?
Ayinde Onitan, ọmọ ọdọ agba.

Lawuyi Ogunniran
O ṣeun l'aiye, Alajao mi,
Iji Alugbe, o o la, o o nii tẹ.
Kafilatu rẹ nkọ ?
Ṣe nbẹ l'alaafia ara ?
Ọba mi oke, Ọba mi isalẹ
Ko ni i jẹ 'hun ti o nfa o ja buẹbuẹ
Ng ko gbagbe ọrọ
Nibi a ba ọrọ de rara
L'ori awọn "ko-s'Ọlọrun" ni
Awọn alakọwe asiko
Ti nwọn npe l'onimọ ijinlẹ.
Mo si ti sọ ohun ti nwọn gbagbọ
Ti nwọn fi sọ pe,
Ko si oloogun ika ati emere,
Ati ohun ti o mu wọn sọ
Pe, ko si Ọlọrun Ọba
Mo si ro pe,
Ọrọ ti tan l'ori eyi baba Kafilatu
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
Ootọ l'o wi, ọmọ Ejigbọjọ,
O ti ṣalaye lekunrẹrẹ
L'ori awọn wọn-un
O si ti sọrọ jinna
L'ori ohun ti nwọn gbagbe duka
Ṣugbọn, Ayinde mo bẹ ọ,
Jẹwọ bi o ba tun ku
Alaye l'ori awọn wọnyi,
Mo fẹ ki o ṣe e delẹ kedere
Nitori alaye t'o nṣe dun leti,
O si kun fun imọ pupọ
Lawuyi Ogunniran
Mo gbọ ohun t'oo wi, ọmọ Ajiṣegiri;
Ṣugbọn mo fẹ ki o ṣe iranti
Pe, ibi a ti bẹrẹ ọrọ wa nilẹ.
Maṣe gbagbe iọẹrẹ pe,
Njẹ oṣo nbẹ, njẹ ajẹ nbẹ,
Njẹ Oloogun ika ati emere nbẹ,
Ni a fi nye ara wa.
Ma jẹ k'a tori ọlọmọwe asiko gbagbe
Ibi ti a ti bẹrẹ ọrọ.
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
O kare l'aiye, ọmọ Ejigbọjọ;
Mo ti ranti l'oot₃
Pe, ibẹ lati bẹrẹ ọrọ wa;
Mo ti ṣe iranti
Ibi a gbe bẹrẹ ọrọ.
Wayi o, ọmọ Ejigbọjọ;
O ti sọ fun mi pe,
Oṣo nbẹ, ajẹ nbẹ,
Oloogun ika ati emere nbẹ;
Ṣugbọn o ko ti i sọrọ bi
Eṣu laalu ba wa.
Lawuyi Ogunniran
Dajudaju, Eṣu laalu nbẹ l'aiye
Ko re ibikankan;
Eṣu laalu nbẹ
O si tun l'ero lẹhin.

Adeyẹmọ Ọjẹrinde
B'o ba ri bayi, ọmọ Ejigbọjọ;
Iru ibaṣe wo l'o wa
Laarin oṣo-ajẹ-emere-oloogun ika
Ati Eṣu laalu, ọkunrin ẹna ?
Lawuyi Ogunniran
O kare l'aiye, ọmọ Ajiṣegiri,
Bẹẹ na l'a kuku u bi ni.
Ara ọmọlẹhin eṣu ni
Oṣo, ajẹ, emere ati oloogun ika wa.
Nkan kanna ni wọn,
Nwọn jọ paṣẹ pọ na ni,
Bi ẹ ba ni babalawo n'ile,
Ki o lọ ree beere wo.
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
Bawo ni babalawo ṣe jẹ si
Gbogbo wọn pata porogodo?
Nwọn jọ nṣiṣẹ ni,
Tabi olukuluku
L'o nṣe tirẹ l'otọọtọ?
Lawuyi Ogunniran
Ohun elo wọn lasan ni
Babalawo jẹ ninu aiye ;
Nwọn a maa lo o
Lati tan ọmọ enia jẹ,
Nwọn a maa lo o
Lati mu ibi ba ọmọ araiye,
Nwọn a maa lo o
Lati fi dẹ okun si
Ọmọ enia l'ọrun.
Ni kukuru, ohun elo lasan ni
Babalawo jẹ fun gbogbo wọn
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
Iru ọna wo ni
Nwọn ngba lo babalawo ?
Ayinde! B'o ba ti ri
Ki o ṣalaye ọrọ ?
Lawuyi Ogunniran
Ajao ọmọ Ajiṣegiri, o tun de !
O nba ọrọ bọ wa sibi
Ki o gbọ ibanujẹ ọrọ.
Ṣe, ko si babalawo n'ile nyin ?
Ṣe bi ko ba si,
Ẹ ko si ni oniṣegun ?
Ṣe babalawo ti ẹ ni
Ko ni eṣu si ode gbangba ?
Ṣe ki i rubọ sidi eṣu na ?
Tabi, o kii ri ese
Ti nwọn i pa silẹ
Ti nwọn i gbe s'oju ode,
Tabi o ko ri ti irona,
O ko ri t'orita ọna ?
Ṣe nigba ti o ri iwọnyi,
O ko mọ pe,
Nwọn nrubọ f'eṣu ni,
Tabi fun oṣo,
Tabi fun ajẹ,
Tabi fun emere
Tabi fun ẹgbẹ atọgba
Ti ngbe'nu okunkun ṣe'hun ara?
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
Ọrọ ija kọ l'ọrọ yi, ọmọ Ejigbọjọ;
Mo fẹ ki o ye mi delẹdelẹ ni,
Mọ f'ori mi bẹ ọ
Ma jẹ k'a sọrọ yi d'ija.
B'o ba d'ọsẹ ta a bọ si
B'Ọlọrun ba wi,
K'a maa ba ọrọ na lọ
Nitori a ki i dagba si
Ohun ti a ko ba mọ.

Hacco Nap
9
32
44

IWE IGBAẸLODE
DARA PUPỌ,
RA TIRẸ NIBẸ
1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 20k
2. Kurani ọgọta esu ni ede Yoruba N10 Esu kan (50k)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati Itumọ (N1)
5 Zabura Yoruba (N1)
6. Iwe Aiye Akamara (N1)
7. Iwe Eniaṣoro (N1) Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (N6); Kekere (50k)
9. Iwe ala ni nla (N2)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun iwosan (N2.50) Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (N1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (50k)
FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:
(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odoye Adeọyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo— Ibadan.

(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi Iṣin St Isalẹ Koto P. O Box 17 Ilọrin.

